# IDAJỌ IKẸHIN ATI IGBALA KURO NI EGIPTI

## Ẹksodu 11:1-10; 12:1-51

## ẸKỌ 56 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "O si fi ayọ̀ mu awọn enia rẹ jade, ati awọn ayanfẹ rẹ pẹlu orin ayọ̀" (Orin Dafidi 105:43).**

**I Ikilọ Ti O Ṣiwaju Idajọ Ikẹhin**

1 Idajọ ikẹhin yoo wá sori gbogbo ilẹ Egipti, lẹhin eyi ni Farao yoo jẹ ki Israẹli lọ, Ẹksodu 11:1; 3:19, 20
2 A paṣẹ fun awọn ọmọ Israẹli lati beere fun diẹ ninu ere iṣẹ ti wọn ti ṣe ni akoko isinru wọn ni Egipti, Ẹksodu 11:2, 3; 3:21, 22
3 Idajọ ikẹhin ni lati pa gbogbo akọbi ni Egipti, eniyan ati ẹranko, Ẹksodu 11:4-6, 8; 4:22, 23
4 Ọlọrun yoo pa Israẹli mọ́ kuro ninu idajọ naa, Ẹksodu 11:7; 8:22, 23
5 Ọkan Farao ti a sé le mú ki o kọ ẹ̀bẹ̀ ikẹhin yi, Ẹksodu 11:9, 10; 10:27-29

**II Ikede Fun Israẹli Nipa Ida-silẹ Ajọ-Irekọja**

1. Niwọn bi idande kuro ni Egipti yoo jẹ apẹẹrẹ idande wa kuro ninu ide ẹ̀ṣẹ, a yàn an fi ṣe ibẹrẹ ọdun titun ekinni, Ẹksodu 12:1, 2; II Kọrinti 5:17; Romu 6:4
2. Wọn ni lati yà ọdọ-agutan irekọja naa sọtọ lati ọjọ kẹwa titi di ọjọ kẹrinla oṣu, Ẹksodu 12:3-6; I Kọrinti 5:7; I Peteru 1:19; Ifihan 5:6
3. Ẹjẹ ẹran naa yoo wà fun igbala wọn, ẹran-ara rẹ yoo si wà fun mimu wọn lokun, Ẹksodu 12:7-13; Numeri 9:12; Johannu 19:33; Heberu 9:22, 28

**III A Da Ajọ-Irekọja Naa silẹ fun Iranti Laelae**

4. Ọlọrun sọ fun wọn pe ajọ naa yoo wà titi fun iranti titi lae tabi ẹri igbala wọn, Ẹksodu 12:14; 13:8-10; Deuteronomi 16:1-8; I Kọrinti 11:23-30
5. Ọlọrun fun wọn ni aṣẹ nipa lilo akara alai wu; iwukara jẹ apẹẹrẹ ẹṣẹ, Ẹksodu 12:15-20; Matteu 16:6; Galatia 5:9
6. A fun Israẹli ni awọn aṣẹ ikẹhin ti wọn yoo tẹ le, Ẹksodu 12:21-28

**IV Idajọ Kẹwa, Eyi ti i ṣe Idajọ Ikẹhin: A Pa Gbogbo Akọbi Egipti**

7. Bi awọn ọmọ Israẹli ti wà labẹ aabo ẹjẹ naa, ni ọganjọ oru, angẹli apa-ni-run bẹ Egipti wò, Ẹksodu 12:29, 30; Heberu 11:28
8. Farao ati awọn ara Egipti rọ̀ awọn ọmọ Israẹli lati jade, Ẹksodu 12:31-34
9. A "kó ẹrù" awọn ara Egipti, eyi ti i ṣe apa kan ninu idajọ ikẹhin, Ẹksodu 12:35, 36; Orin Dafidi 105:36-38

**V Ijade Lọ Kuro Ni Egipti**

1 Ni ọna àra ati iyanu nla ogunlọgọ awọn ọmọ Israẹli fi Egipti silẹ, Ẹksodu 12:37-42; Orin Dafidi 78:5-53; Gẹnẹsisi 15:13-16; Galatia 3:17
2 A fi ibẹrẹ Ofin ti Ajọ-Irekọja lelẹ, Ẹksodu 12:43-51

## ALAYE

### Awọn Ikilọ Aanu

Ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun ti o wi pe "Nigbati emi ba ri ẹjẹ nã, emi o ré nyin kọja" jẹ kókó pataki ti o n bẹ ninu ẹkọ́ yi, ẹkọ́ yi n sọ nipa ọkan ninu paṣan idajọ ti o wa sori Egipti, ati ipinya patapata laarin awọn abọriṣa wọnni ati awọn eniyan Ọlọrun. Ijade lọ ti o tẹ le e jẹ ọwọ́n pataki kan ninu itan awọn ọmọ Isaẹli, o si jẹ ibẹrẹ orilẹ-ede wọn. Wọn di ominira nisinsinyi lati tẹle Oluwa ni ọna ti O yàn fun wọn. A le ri i kedere pe apẹẹrẹ irapada wa kuro ninu ẹ̀ṣẹ ni o jẹ; bi a si ti n kà a yoo dun mọ wa lati ri ọpọ nkan ti o dọgba pẹlu ẹkọ Idalare nipa igbagbọ́.

Ọlọrun ti mú suuru pẹlu awọn eniyan Egipti, O ti gbiyanju lati dari wọn kuro ninu ibọriṣa si isin otitọ; ṣugbọn ogunlọgọ ninu wọn ni o yàn sisin èké wọn dipo. A kò mọ iye awọn ti o gba Ọlọrun Israẹli gbọ́ nikẹhin. Awọn kan ni ibẹru nla fun Ọlọrun laarin wọn, ṣugbọn Bibeli kò sọ fun ni bi awọn diẹ wọnyi ti ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn to.

Lati ibẹrẹ ni a ti sọ fun Farao pe akọbi Ọlọrun ni Israẹli i ṣe; bi kò ba si da wọn silẹ, akọbi Egipti yoo kú (Ẹksodu 4:22, 23). Farao kọ̀ lati gbọran, ṣugbọn Ọlọrun kò ran idajọ ikẹhin yi lẹsẹkẹsẹ. Kaka bẹẹ, Ọlọrun mu suuru fun Farao. Ọlọrun ran idajọ mẹsan ti ko buru pupọ bi ti ikẹhin ti a leri rẹ wá sori awọn ara Egipti, lati fi kọ́ wọn pe Oun ni o ni gbogbo agbara ati pe omulẹ-mofo lasan ni awọn oriṣa ti wọn. Nitori naa, wọn kò lagbara, ṣugbọn wọn kò gba pe ki a kọ wọn.

**Ipinya Laarin Egipti ati Israẹli**

O jọ ni loju bi Ọlọrun ti daabo bo Israẹli to kuro ninu idajọ gbigbona wọnni; nitori ti wọn bu ọlá fun Un, wọn bẹru Rẹ̀, wọn si gbọran si I lẹnu. Gọngọ idajọ ti o sọ nikẹhin jẹ lati mú ipinya ti o tobi ju bẹẹ lọ wá saarin Egipti ati Israẹli. A ṣe eto rẹ pe ki Israẹli ki o sa ipá kan ki o ba le wà lai lewu nigba ti angẹli apanirun ba de, bi wọn ba si gbọran si Ọlọrun lẹnu, aabo Rẹ̀ yoo jẹ ti wọn. Ni ọna miran gbogbo o dabi ẹni pe aanu Ọlọrun ṣiji bo wọn lai tilẹ jẹ pe wọn beere fun eyi; ṣugbọn nihin a beere lọwọ wọn lati fi ijẹwọ igbagbọ́ wọn ninu Ọlọrun hàn (Heberu 11:28).

Iṣẹlẹ ribiribi yi ninu igbesi-aye awọn ọmọ Israẹli ṣe pataki to bẹẹ ti Ọlọrun fi paṣẹ fun wọn lati bẹrẹ si i ka ọdun wọn ni ọjọ naa. Ṣaaju eyi, won ti n tẹle aṣa Egipti lati bẹrẹ ọdun titun nigba ikore. Ṣugbọn nisinsinyi Ọlọrun n fẹ ki won pa ohun gbogbo ti yoo mu wọn ranti Egipti ti si apa kan ki won si jẹ eniyan ọ̀tọ̀ fun Oun. Ọlọrun kò fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ maa ṣe bi awọn eniyan aye, ki wọn jọ aye, tabi ki wọn tẹ le ẹ̀mí ti n ṣakoso wọn. O mọ̀ pe eyikeyi ninu iwa tabi aṣa Egipti ti awọn ọmọ Israẹli ba di mu yoo mu wọn kuro lọdọ Rẹ̀ nikẹhin.

Ẹṣẹ ki i fi igba gbogbo ni ibẹrẹ titobi. Eniyan ti o ba kọ̀ Ọlọrun silẹ ki i fi igba gbogbo ṣe bẹẹ pẹlu igbesẹ nla kan ṣoṣo. Kàkà bẹẹ, iyapa diẹdiẹ ni o maa n wà titi a o fi yà oluwa rẹ̀ nipa pẹlu Ọlọrun. Bi ẹni kan ba fi oju rẹ sinu aye, oun yoo maa poungbẹ fun awọn nkan ti kò ni laari ti o le dabi ẹni pe kò lewu, ṣugbọn ti yoo gba aye kan ti Ọlọrun ti ni ri ninu aye rẹ. Ohunkohun ti o ba dipo Ọlọrun ninu ọkan a, oriṣa ni: nitori bẹẹ iyapa yi jẹ oriṣa kan. Ohun ti ko ṣe e di mu le jẹ oriṣa: i8pinnu lasan tabi ero ọpọlọ eniyan le jẹ oriṣa. Ohunkohun ti o ba dipo Ọlọrun ninu ọkan wa, ninu akoko wa, tabi ninu ifẹ wa, o lodi, bi o ba si pẹ lọ titi nibẹ, yoo mu a kuro lọdọ Ọlọrun nikẹhin. Nitori idi eyi Ọlọrun fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ yẹra kuro ninu ohun gbogbo ti yoo mu wọn ranti Egipti.

**Ase Ajọ-Irekọja ati Irubọ**

Ọjọ kinni oṣu Abibu (ti o fẹrẹ bọ si oṣu kẹrin ọdun (April ti wa) ni yoo wa jẹ ọjọ kinni ọdun Titun ti wọn. Ni ọjọ kẹwa oṣu naa ni wọn ni lati yan ọdọ-agutan kan ti o pé lati inu agbo wọn, ti kò gbọdọ dagba ju ọdun kan lọ. Wọn ni lati ya ọdọ-agutan yi sọtọ kuro ninu agbo-ẹran ki a si fun un ni ounjẹ lọtọ̀ titi di aṣalẹ ọjọ kẹrinla nigba ti a o pa a .

Ọjọ awọn Ju bẹrẹ nigba ti oorun ba wọ̀ dipo ọganjọ oru, apa kinni ọjọ ti wọn si ṣe deedee pẹlu aṣalẹ ti wa. Akókò ti o kẹhin ọjọ ti wọn jẹ ọsan ti wa wọn si n pe e ni aṣalẹ pẹlu. A ti pa ọdọ-agutan naa ni ipari aṣalẹ ọjọ kẹrinla, wọn o si jẹ àse naa lẹhin ti wọn ba ti sun ọdọ-agutan naa, titi di **aṣalẹ** ọjọ kẹẹdogun oṣu naa. Awọn kan ti n kẹkọ nipa ọjọ ti nkan n ṣẹlẹ ninu Bibeli gbagbọ́ pe irekọja ikẹhin, nigba ti a kan Jesu mọ́ agbelebu, bọ́ si ọjọ kan naa ninu ọsẹ ti a ṣe ti akọ́kọ́.

**Ọdọ-agutan Ọlọrun**

Ifara we ti o mu ni lọkan kan wa laarin ọdọ-agutan irekọja ati Ọdọ-agutan Irekọja nla nì, ani Jesu Kristi (I Kọrinti 5:7); Johannu 1:29). Jesu mu irekọja ṣẹ nipa ọpọlọpọ iṣẹlẹ ti o so mọ ara wọn bi ẹwọn, ti wọn si ṣẹ ni deedee akoko; eyi si fi han pe ki i ṣe pe wọn kan deedee ṣẹlẹ tabi wọn kan ṣe kongẹ akoko kan ṣaa. O gun ẹṣin wọ inu ilu Jerusalẹmu ni iṣẹgun lati mu apẹẹrẹ ọdọ-agutan ti a ya sọtọ ni ọjọ kẹwa oṣu ṣẹ. Akoko ti o pọju ninu awọn ọjọ ti o tẹ lee ni o lò pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ ti O fẹran. Ni wakati naa gan an ti wọn maa n pa ọdọ-agutan irekọja ni o kú; nipa eyi ti o fi mú apẹẹrẹ inu Majẹmu Laelae ṣẹ lọna iyanu; ki i si ṣe nitori ọgbẹ́ ti awọn eniyan ṣá A, nitori iya lẹnu awọn ọmọ-ogun lati ri i pe Jesu ti kú fi hàn pe ikú Rẹ̀ tete de.

Dajudaju Jesu ni Ọdọ-agutan ti kò ni eeri tabi abuku. Ko si ọkan ninu awọn egungun Rẹ̀ ti a ṣẹ́ -- eyi ti o tun jẹ imuṣẹ kedere asọtẹlẹ ati apẹẹrẹ, O kú ki a ba le di ominira, O si sanwo irapada fun gbogbo ẹni ti yoo ba fi ṣe dandan lati ri i pe a fi Ẹjẹ naa wẹ ọkan wọn.

Jesu jẹ Ase Irekọja pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ ṣiwaju ikú Rẹ̀. Eyi ṣẹlẹ ni ọjọ naa gan an ti Ọlọrun ti fi lelẹ pe o tọ fun pipa ati jijẹ irekọja. Gẹgẹ bi oye wa ti mọ, ofin kò sọ pato wakati ọjọ eyi ti won ni lati jẹ Irekọja naa; diẹ ninu awọn Ju a si maa tete jẹ Irekọja nigba ti eyi ba bọ si Ọjọ Isinmi ti wọn maa n ṣe ni ọsọọsẹ. Wọn n ṣe eyi ki pipa Ajọ Irekọja mọ ma baa papọ mọ pipa ọjọ isinmi ọsọọsẹ mọ.

Ihinrere Johannu (Johannu 18:28) fi hàn pe Kristi jẹ Irekọja ṣiwaju awọn Ju miran. Ti pe eyi si ba ofin mu hàn ni ti otitọ ni pe nigba gbogbo ni Jesu pa Ofin mọ ni kinni kinni, ati ni ti pe awọn ọmọ-ẹhin wà ni ifohun ṣọkan, wọn kò si ja A niyan nipa akoko ti O yàn.

**Nigba ti Angẹli Apanirun De**

Gbogbo iwukara ni a ni lati mu kuro ninu ile awọn ọmọ-Israẹli. Wọn si fara balẹ ṣe eyi, eyi ni pe gbogbo kọ̀rọ̀ ile wọn ni wọn yẹ wò ni finni finni ki wọn to bẹrẹ ounjẹ naa. Lakoko Majẹmu Laelae iwukara jẹ apẹẹrẹ ẹ̀ṣẹ; niwọn bi Ase Irekọja si ti jẹ apẹẹrẹ idalare wa nipa igbagbọ́, a le ri i kedere bi mimu iwukara kuro ti ba apẹẹrẹ naa mu, nitori ẹlẹṣẹ ni lati kọ́kọ́ yi pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ ki o si kọ ọ silẹ bi o ba n fẹ ki a gba oun la (Isaiah 55:7).

Angẹli apanirun la ilẹ Egipti kọja ni ọganjọ oru o si pa akọbi eniyan ati ti ẹranko. Ṣugbọn nigba ti angẹli naa ba ri ẹ̀jẹ lara ile kan oun a ré ile naa kọja oun a si dá awọn olugbe ile naa si. Ẹjẹ ti o wa lara ọdọ-agutan naa, tabi eyi

ti o wa ninu awo, kò ṣe wọn lanfaani ayafi igba ti won ba lo o gẹgẹ bi Ọlọrun ti pa a laṣẹ. Ibi aabo wa, nigba ti a ba tú ibinu Ọlọrun Olodumare sori awọn ẹlẹṣẹ, n bẹ labẹ Ẹjẹ naa. A ni lati fi wọ́n ẹnu-ọna ọkan wa – ki o to le ṣiṣẹ.

Oluwa ti kilọ ṣiwaju, ṣugbọn nisinsinyi O kọlu wọn! Ogo agbo-ile kú, aayo ati ọ̀ṣọ́ orilẹ-ède naa ni a ké kuro -- awọn alagbara ni ogun, arole awọn ọlọrọ, ati ireti awọn talaka, gbogbo wọn ni o ku laarin ọganjọ. Farao ti pa akọbi Ọlọrun, Oluwa si san an pada fun un loju rẹ. Dajudaju "ohun ẹru ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọrun alãye" (Heberu 10;31).

Iwe itan ati iriri awọn onimọ-ijinlẹ nipa ilẹ wiwà jẹri si ajalu nla yi. Ni Gbọ̀ngan Itọju ohun Atijọ ni Berlin eré nla kan ti a gbẹ́ wà nibẹ eyi ti o ni lati jẹ ti Farao ti o wà ni akoko ijade lọ awọn ọmọ Israẹli kuro ni Egipti, pẹlu ọmọ rẹ ti i ṣe arole si itẹ. Diẹ ni a mọ̀ nipa ọmọkunrin yi, aburo rẹ ọkunrin ni o si jẹ ọba dipo rẹ. A si ti ri awọn akọsilẹ ti o fi han pe iṣẹlẹ ajeji kan ti ṣẹlẹ ni orilẹ-ède naa nigba aye Farao ọba yi, ati pẹlu pe akọbi rẹ ọkunrin kú lọna abàmi. O jẹ aṣa awọn ọba igbà nì lati maa kọ kiki iṣgun wọn nikan silẹ, wọn ki i saba maa fi ẹnu kan iṣubu wọn, nitori bẹẹ diẹ ni awọn akọsilẹ ti o wa nilẹ; ṣugbọn awọn diẹ naa jẹri gidigidi si otitọ akọsilẹ Iwe Mimọ́.

**Orilẹ-ède ti A Bí Ni Alẹ Ọkọ Kan**

Awọn ara Egipti ri ohun kan ti wọn ko gburo rẹ ri ni alẹ ọjọ yi. Nkan bi adọjọ ọ̀kẹ́ (3,000,000) eniyan pẹlu agbo-ẹran ati ọ̀wọ́-ẹran wọn gbera, wọn si lọ. Ijade lọ nla yi jọ ni loju siwaju si i ni ti pe awamaridi ọwọ Oluwa ni o tọ́ ogunlọgọ eniyan wọnyi jade. Agbara Ọlọrun nikan ni o le pilẹ rẹ ki o si ṣe e yọri – ki a má tilẹ sọ nipa pipese fun ogunlọgọ awọn eniyan bi iru eyi ninu aginju nibi ti a kò ti le ri awọn nkan ti o jẹ kò se e ma ni fun ara.

Wọn pọ niye gidigidi. Sibẹ kò si ẹni kan ti o wà ni ile itọju awọn alaisan, a kò gbe ẹnikẹni sinu kẹkẹ olokunrun, bẹẹ ni ko si ẹni kan ti o fa sẹhin nitori ti ẹsẹ n dun laarin wọn. Ipọnju ati ìṣẹ́ le ti sọ wọn di alai lera, ṣugbọn Ọlọrun ti mu wọn larada. Kò si arun Egipti kankan lara wọn. Eyi fi hàn wa pe nigba ti Ọlorun ba pe ni lati lọ si ibi kan Oun yoo ṣe wa yẹ fun irin-ajo naa. Ninu irin-ajo wa laye agbara wa yoo pọ bi ọjọ aye wa.

Ijade kuro ni Egipti yi ni o pari ọgbọnlenirinwo (430) ọdun irin-ajo ti o bẹrẹ nigba ti Ọlọrun ba Abrahamu dá majẹmu (Galatia 3:17). Lati igba ti Abahamu ti wo ilẹ Kenaani ti a si fun un ni majẹmu, titi di akoko ti Jakọbu fi lọ si Egipti nigba ti ọmọ rẹ Josẹfu pe e jẹ okoolerugba ọdun o din marun (215). Jakọbu ati awọn iran rẹ wà ni Egipti fun okoolerugba ọdun o din marun (215); apapọ gbogbo rẹ jẹ ọgbọnlenirinwo (430) ọdun ti a sọ nipa rẹ ninu ẹ̀kọ́ wa.

Awọn ọmọ Israẹli jade kuro ni Egipti gẹgẹ bi ajagun-ṣẹgun nipa agbara Jehofa Ọlọrun wọn. Wọn ti wa si Egipti gẹgẹ bi darandaran ti o kere niye, nigba ti wọn si wà nibẹ a mu won sin isìnru iru eyi ti o rẹlẹ̀ ju lọ; ṣugbọn wọn jade nibẹ pẹlu iṣura Egipti, eyi ti a fi fun won nigba ti wọn beere lọwọ awọn ara Egipti fun èrè ti o tọ́ fun laalaa wọn. A ko ran wọn jade nipa gbigbọjẹgẹ fun ijade lọ wọn, eyi ti i ba mu itiju dani, bi ko ṣe pẹlu gbogbo nkan ti wọn ti beere lakọkọ, nitori ti wọn gbọran si Ọlọrun ọrun ti wọn si duro de akoko igbala Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Darukọ awọn idajọ, tabi arun mẹwa ti a ran si Egipti.
2. N jẹ Farao mọ̀ nigba ti a rán idajọ kinni wá, pe kikọ̀ lati gbọran si Ọlọrun lẹnu yoo yọri si idajọ kẹwa yi?
3. Awọn wo ni o bọ́ lọwọ idajọ kẹwa?
4. Sọ ofin Ajọ Irekọja.
5. Ẹsẹ ọrọ wo ninu ẹ̀kọ́ yi ni iwọ ro pe o ṣe pataki ju lọ?
6. Aabo wo ni a fi fun ni labẹ Ẹjẹ Kristi?
7. Bawọ ni wọn yoo ti maa ṣe Ajọ Irekọja leralera to?
8. Kin ni Ajọ Irekọja duro fun?
9. Apẹẹrẹ kin ni Ajọ Irekọja jẹ?
10. Apẹẹrẹ kin ni iwukara jẹ?